
**Láti ọwọ́ Ààrẹ Thomas S. Monson**



# Fi Àyè Sílẹ̀ FunOlùgbàlà

Àsìkò Kérésìmesì Míràn ti wá sórí wa àti pẹ̀lú rẹ̀ ni ìbẹ̀rẹ̀ ọdún tuntun kan. Ó dàbíi pé àná nìkan ni à ṣì ṣayẹyẹ ọjọ́ ìbí Olùgbàlà tí a sì nṣe àwọn ìpinnu.

Ní ààrín àwọn ìpinnu wa fún ọdún yí, njẹ́ a pinnu láti fi àkokò nínú ayé wa àti àyè nínú ọkàn wa fún Olùgbàlà? Bí ó ti wù kí a ṣe àṣeyọrí sí tó pẹ̀lú irú ìpinnu náà, mo nídánilójú pé a nífẹ́ láti ṣe dáadáa si. Àsìkò Kérésìmesì yí ni ìgbà pipe láti ṣàyẹ̀wò kí a sì tún ìgbìyànjú wa ṣe.

Nínú ayé aápọn wa, pẹ̀lú ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ohun míràn tó ndíje fún ìfọnkansí wa, ó ṣe pàtàkì pé kí a mọ̀ sínú, kí a sì ní ìtẹramọ́ ìgbìyànjú láti mú Krístì wá sínú ayé wa àti ilé wa. Ó sì ṣe kókó kí àwa náà, bíi ti àwọn Ọlọ́gbọ́n Ọkùnrin láti Ìlà Oòrùn, dúró ní ìkọjúsí lórí ìràwọ̀ Rẹ̀ àti pé "kí a wá láti jọ́sìn fún un."[1]

Silẹ̀ nínú àwọn ìran ti àkokò, ọ̀rọ̀ náà látẹnu Jésù ti jẹ́ bákannáà. Sí Pétérù àti Ándérù níbi èbúté Gálílì, Ó sọ pé, "Tẹ̀lé mi."[2] Sí Fílípì ni ìpè náà wá pé, "Tẹ̀lé mi."[3] Sí Ará Léfì ẹni tí ó jókó níbi gbígba nkan ti àwọn oníbodè ni àṣẹ tiwá pé, Tẹ̀lé mi."[4] Àti sí ìwọ àti sí èmi, ṣùgbọ́n tí a bá fetísílẹ̀, ni irú ìjuwọ́ ìfipè náà yíò wá pé: "Tẹ̀lé mi."[5]

Gẹ́gẹ́bí a bá ṣe ntẹ̀lé àwọn ìṣísẹ̀ Rẹ̀ lóní àti pé bí a ṣe ndura láti tẹ̀lé àpẹrẹ Rẹ̀, a ó ní àwọn ànfàní láti bùkún ayé àwọn ẹlòmíràn. Jésù pè wá láti fi ara wa sílẹ̀: "Kíyèsíi, Olùwa bèèrè fún ọkàn àti ìfẹ́ inú kan."[6]

Njẹ́ ẹnìkan wà tí ìwọ níláti pèsè iṣẹ́ ìsìn fún ní Kérésìmesì yí? Njẹ́ ẹnìkan wà tí ó ndúró de ìbẹ̀wò rẹ

Ọ̀pọ̀ ọdún sẹ́hìn mo lọ fún ìkíni Kérésìmesì nílé àgbàlagbà opó kan. Nígbàtí mo wà níbẹ̀, aago ẹnu ọ̀nà náà dún. Níbẹ̀ ní ẹnu ọ̀nà náà ni Olùwòsàn alaápọn olókìkí kan gidi dúró sí. Kò sẹ́ni tó pèé wábẹ̀; ṣùgbọ́n, ó kàn ní ìṣílétí kan ni láti ṣèbẹ̀wò sí alaárẹ̀ kan tí ó nìkanwà.

Ní ààrín àsìkò yí, ọkàn àwọn tí ó wà ní àhámọ́ nnawọ́ síta wọ́n sì nṣe ìyọ́nú fún ìbẹ̀wò Kérésìmesì kan. Kérésìmesì kan nígbàtí mò nbẹ gbàgede ìtọ́jú kan wò, mo jókó mo sì sọ̀rọ̀ pẹ̀lú àwọn omidan àgbàlagbà márún, èyí tí ẹni tó dàgbà jù lára wọn jẹ́ ọmọ ọdún ọgọ́ọ̀rùn ó lé kan. Ó fọ́ lójú, síbẹ̀síbẹ̀ ó dá ohùn mi mọ̀.

"Bíṣọ́ọ̀pù, ó pẹ ọ díẹ̀ lọ́dún yí!" ni ó sọ. "Mo rò pé o kò ní wá mọ́ rárá."

A ní àkokò kan dáradára papọ̀ pẹ̀lú Aláárẹ̀ kan, bákannáà Ọ̀ nwòta fèrèsé pẹ̀lú ìfojúsọ́nà àti pé ó nṣàtúnsọ lẹ́ẹ̀kan àti lẹ́ẹ̀kan si pé, "Mo mọ̀ pé ọ̀dọ́mọkùnrin mi yíò wá láti rí mi lóní." Mo níyanu bóyá yíò wá, nítorí àwọn àsìkò Kérésìmesì míràn ti wà nígbàtí kò pè rárá.

Àkókò ṣì wà lọ́dún yí láti nawọ́ ìrànlọ́wọ́ sí, olólùfẹ́ ọkàn náà, àti ẹ̀mí tó nífẹ́ – ní àwọn ọ̀rọ̀ míràn, láti tẹ̀lé àpẹrẹ náà tí Olùgbàlà wa gbé kalẹ̀ àti láti sìn bí Òun yíò ṣe fẹ́ kí a sìn. Gẹ́gẹ́bí a ṣe nsìn Ín, a kò ní pàdánù ànfàní wa, bí ti àwọn olùpamọ́ ilé ìtura ti àtijọ́,[7] láti fún Un ní àkokò nínú ayé wa àti àyè fun Un nínú ọkàn wa.

Ṣe a lè ní òye ìlérí títóbi tó wà nínú ọ̀rọ̀ tí ángẹ́l fifún àwọn olùṣọ́ àgùtàn tí wọ́n wà nínú pápá: "Mo mú ìròhìn

ayọ̀ ńlá wá fún yín. . . . Nítorí a bí Olùgbàlà . . . fún yín lóní, èyí tíí ṣe Krístì Olúwa"?[8]

Bí a ṣe nṣe pàṣípààrọ̀ àwọn ẹ̀bùn ní Kérésìmesì, njẹ́ kí a rantí, moyì, kí a sì gba ẹ̀bùn nlá jùlọ tó ju gbogbo àwọn ẹ̀bùn lọ – ẹ̀bùn ti Olùgbàlà àti Olùràpadà wa, kí a lè ní ìyè ayérayé.

"Nítorí èrè kilo jẹ́ fún ènìyàn tí a ba fun ni ẹ̀bùn, tí kò sì gba ẹ̀bùn náà? Kíyèsíi, kò dunnú sí èyí tí a fifun, bẹ́ẹ̀ni kò sì dunnú nínú ẹni tí ó jẹ́ olùfúnni ní ẹ̀bùn náà."[9]

Njẹ́ kí a tẹ̀lé E, sìn Ín, bu ọlá fún Un, kí a sì gba ẹ̀bùn Rẹ̀ sí wa nínú ayé wa, pé kí a lè wà, nínú àwọn ọ̀rọ̀ Bàbá Léhì, "wà nínú apá ìfẹ́ ayérayé rẹ̀."[10]

**ÀWỌN ÀKỌSÍLẸ̀ RÁNPẸ́**

1. Matteu 2:2
2. Matteu 4:19 .
3. Johannu 1:43
4. Matteu 9:9
5. Ẹkọ̀ àti Àwọn Májẹmú 38:22
6. Ẹkọ̀ àti Àwọn Májẹmú 64:34
7. RíLúkù 2:7
8. Lúkù 2:10–11
9. Ẹkọ̀ àti Àwọn Májẹmú 88:63
10. 2 Nífâì 1:51

## ẸKỌ LÁTINÚ ỌRỌ YÍ

Ààrẹ Monson pè wá láti "ní ìmọ̀sínú kan, ìtẹ̀ramọ́ ìgbìyànjú láti mú Krístì wá sínú ayé wa àti sínú ilé wa.", Gbèrò sísọ̀rọ̀ pẹ̀lú àwọn wọnnì tí ò nkọ́ bí wọ́n ṣe lè ṣe ìgbìyànjú ìmọ̀sínú níkọ̀ọ̀kàn àti gẹ́gẹ́bí ẹbí kan. Ó lè gbèrò bíbèèrè lọ́wọ́ wọn láti ronú nípa ẹnìkan tàbí ẹbí èyítí wọ́n lè bẹ̀wò tàbí sìn ní Kérésìmesì yí. "Àkokò ṣì wà síbẹ̀síbẹ̀ lọ́dún yí láti nawọ́ ìrànlọ́wọ́, olùfẹ́ ọkàn àti ẹ̀mí tó nífẹ́."

## ỌDỌ́

## Àwọn ọ̀nà láti Sìn ní Àkokò Kérésìmesì

Ààrẹ Monson mú àkokò láti bẹ àwọn àgbàlagbà wò àti àwọn wọnnì tó wà ní gbàgede ìtọ́jú, nípàtàkì ní àkokò Kérésìmesì. Ó Ṣàkíyèsí pé àwọn wọnnì wà tí inú wọn dùn nítorí wọ́n ti gba àwọn àlejò, nígbàtí àwọn míràn kàn n nírètí fún àwọn olùbẹ̀wò tí kò wá rárá. Àwọn ènìyàn kan wà tí wọ́n ndúró de ẹnìkan – bóyá ní Kérésìmesì yí, *o* lè jẹ́ ẹnìkan náà.

Àtẹ̀lé àkójọ yii ni orúkọ àwọn ọ̀nà díẹ̀ tí a lè fi ṣèrànwọ́ láti ri dájú pè kò sí ẹnikẹ́ni tó ní ìmọ̀ara àdánìkanwà ní Kérésìmesì yí. Ní ìmọ̀ara ìtúnúká láti ronú nípa àwọn ọ̀nà síi láti nawọ́ jade sí àwọn ará ìlú yín ní àsìkò yí. "Ṣé ọ̀kan wà tó ndúró de ìbẹ̀wò yín?

- Ṣe àwọn káàdì Kérésìmesì láti firánṣẹ́ sí àwọn ìrànṣẹ́ ìhìnrere àti àwọn àpọ́n àti àwọn ọmọ ìjọ wọ́ọ̀dù tàbí ẹ̀ká yín.
- Olùfarasìn ọ̀fẹ́ kan pẹ̀lú ìjọba ìbílẹ̀.
- Fi àwọn ẹ̀dà ti Ìwé Mọ́rmọ́nì gẹ́gẹ́bí ẹ̀bùn Kérésìmesì fún àwọn ọ̀ré àti àwọn aládúgbò rẹ.
- Bẹ àwọn àgbàlágbà ènìyàn wò ní wọ́ọ̀dù rẹ tàbí ẹbí.
- Ṣe àwọn àpèjẹ láti gbé fún àwọn aládúgbò rẹ.

## ÀWỌN ỌMỌDÉ

## Tẹlé Ìmọ́lẹ̀ náà

Lẹ́hìn tí a ti bí Jésù, àwọn Amoye kan mú àwọn ẹ̀bùn wá fún Un. Wọ́n tẹ̀lé ìràwọ̀ dídán tuntun kan, ní ojú ọ̀run láti rí I. Kíni àwọn ẹ̀bùn tí ìwọ lè fún Jésù ní Kérésìmesì yí?

© ọdún 2015 ípasẹ̀ Intellectual Reserve, Inc. All rights reserved A tẹ ní USA Àṣẹ Gẹẹsì 6/15. Àṣẹ ìyíròpadà èdè 6/15.
Ìyíròpadà èdè ti *First Presidency Message, December 2015.* Yoruba. 12592 779

# Àwọn Ìhùwàsí ti Jésù Krístì Aláánú àti Onínúrere

*Fitàdúrà-tàdúrà ka ohun èlò yĩ kí o sì ṣe àwárí lati mọ ohun ti õ ṣe àbápín Báwo ni níní òye awọn ìhùwàsí àtọrunwá ti Olùgbàlà ṣe nmú ìgbàgbọ yin ninu Rẹ pọ sĩi ati kí ẹ bùkún awọn tí ẹ nṣe ìṣọ lé lórí nipa ìbẹniwò kíkọni? **Fún ìmọ̀ sĩi, lọ sí reliefsociety.lds.org**.*

**Ìgbàgbọ́, Ẹbí, Ìrànlọ́wọ́**

*Èyí ni apákan onírurú àwọn Ọrọ Ìbẹniwò Kíkọni tí ó ńfi ìhùwàsí àtọrunwá ti Olùgbàlà hàn.*

"Nínú àwọn ìwé mímọ́, bí ọ̀rọ̀ ti rí àánú túmọ̀ sí 'láti jìyà pẹ̀lú.' Bákannáà ó túmọ̀sí láti fi ìbákẹ́dùn, àánú, àti ìyọ́nú fún ẹlòmíràn hàn[1]

"Jésù pèsè ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn àpẹrẹ ti àníyàn ìkáánú fún wa," ni Ààrẹ Thomas S. Monson sọ. "Ọkùnrin arọ náà níbi odò Bẹ́tsáídà; obìnrin tí wọ́n mú nínú àgbèrè; obìnrin níbi kanga ti Jákọ́bù; ọmọbìnrin Jáírù; Lásárù, arákùnrin Màríà àti Márthà – ìkọ̀ọ̀kan jẹ́ aṣojú kan fún olùfarapa ní òpópónà Jẹ́ríkò. Ìkọ̀ọ̀kan nílò ìrànlọ́wọ́.

"Sí arọ náà ní Bẹ́tsáídà, Jésù sọ pé, 'Dìde, gbéra rẹ, kí o sì máa rìn.' Sí obìnrin ẹlẹ́ṣẹ̀ náà ni ìmọ̀ràn náà wá pé, 'Lọ, kí o máṣe dẹ́ṣẹ̀ mọ́.' Láti ràn ẹni náà tí ó wá láti fa omi lọ́wọ́, Ó pèsè kanga omi kan tó nsun jade sínú ìyè ayérayé.' Sí òkú ọmọbìnrin Jáírù ni àṣẹ wá pé, 'Omidàn, mo wí fún ọ, dìde.' Sí Lásárù tí a ti sìn, 'jáde wá.'

"Olùgbàlà ti fìgbàgbogbo fi àìlópin agbára hàn fún àánú. . . . jẹ́ kí a ṣí ilẹ̀kùn ọkàn wa, kí Òun – àpẹrẹ alàáyè ti àánú òtítọ́ – lè wọlé."[2]

### Àfikún Àwọn Ìwé Mímọ́

Ìwé Orin 145:8; Zecharíàh 7:9; 1 Pétérù 3:8; Mòsíàh 15:1, 9; 3 Nífáì 17:5–7

### Látinú Àwọn Ìwé Mímọ́

"Ọkọ mi àti èmi kúnlẹ̀ ní ẹ̀gbẹ́ ọmọbìnrin ọdún mẹ́tàdínlógún wa a sì bẹ̀bẹ̀ fún ẹ̀mí rẹ̀," ni Linda S. Reeves olùdámọ̀ràn kejì nínú àjọ ààrẹ Ẹgbẹ́ Ìrànlọ́wọ́ gbogboògbò sọ "Ìdáhùn náà ni rárá, ṣùgbọ́n . . . a ti wá láti mọ̀ . . . pé . . . [Olùgbàlà náà] ní ìmọ̀lọ́kàn àánú fún wa nínú ìbànújẹ́ wa."

"Ìkan nínú àwọn àyànfẹ́ ìtàn mi látinú ìgbé ayé ti Olùgbàlà ni ìtàn Lásárù. Àwọn ìwé mímọ́ sọ fún wa pé 'Jésù fẹ́ràn Márthà, . . . arábìnrin rẹ̀ [Màríà], àti [arákùnrin wọn] Lásárù.'",[4] Nígbàtí Lásárù di aláàrẹ̀, wọ́n sì lọ sọ fún Jésù, ṣùgbọ́n nígbàtí Ó dé Lásárù ti kú ṣíwájú. Màríà sáré lọ bá Jésù, ó dùbúlẹ̀ lé ẹ̀sẹ̀ Rẹ̀, ó sì sọkún. Nígbàtí Jésù rí Màríà tó nsọkún, "ó sìn nírora nínú ẹ̀mí, ó sì . . . sọkún" (Jòhánù 11:33, 35).

"Ìyẹn ni àṣẹ wa. A gbọ́dọ̀ ní ìmọ̀lára kí a sì rii fúnra wa àti pé nigbànáà kí a ràn gbogbo àwọn ọmọ ti Bàbá Ọ̀run lọ́wọ́ láti ní ìmọ̀lára àti láti rí àti láti mọ̀ pé Olùgbàlà wa kò gbé gbogbo àwọn ẹ̀ṣẹ̀ wa sórí ara rẹ̀ nìkan ṣùgbọ́n bákannáà àwọn ìròra wa àti ìjìyà wa àti àwọn ìpọ́njú wa kí Ó ba lè mọ̀ ohun tí à nní ìmọ̀lára rẹ̀ àti bí ó ṣe lè tù wá nínú."[5]

#### ÀWỌN ÀKỌSÍLẸ̀ RÁŃPẸ́

1. Ìtọ́sọ́nà sí àwọn Ìwé Mímọ́, "Àánú."
2. Thomas S. Monson, "Ẹ̀bùn ti Àánú," *Amọ̀nà,* Oṣù Kéta, Ọdún 2007, 4–5, 8.
3. Linda S. Reeves, "Olúwa kò Tĩ Gbàgbé Rẹ," *Amọ̀nà* Oṣù Kọkànlá. Ọdún 2012, 120
4. Linda S. Reeves, "Olúwa Kò Tĩ Gbàgbé Rẹ," 118
5. Linda S. Reeves, "Olúwa Kò Tĩ Gbàgbé Rẹ," 120

### Gbèrò Èyí

Tani ó lè di alábùkún nípa àánú rẹ?

© 2015 nípasẹ̀ Intellectual Reserve IncAll rights reserved A tẹ̀ ní USA Àṣẹ Gẹẹsì 6/15. Àṣẹ ìyírọ̀padà èdè 6/15.
Ìyírọ̀padà èdè ti *Visiting Teaching Message, December 2015.* Yoruba. 12592 779